# ERE ORI ITAGE.

Sasha Kasthuriarachchi.

**AWON OSERE:**

**Alex- Omokunrin Peter ati Helen**
**Graham- Ore Tina**
**Helen- Aya Peter**
**Jayne- Olugbani nimoran**
**Julie- Noosi**
**Peter- Oko Helen**
**Tina- Ale Peter.**

**AWON OSERE MIRAN:**
**Awon noosi, ati awon onise ile itura.**

**IFIHAN KINI.**

**A ri Helen ninu ile idana, o n n mura lati se onje. O si li oyun sinu. Oko re Peter joko o si n ka iwe iroyin, o fi aso re ko ara ijoko.apo iwe kan fi ara ti tabili kan ninu nile naa. Bi o tile je wipe awon mejeji dake, sibe a n gbo iro omode kan ti n n sa kaakiri inu ile, ti o si n rerin ninu yara ti o fi ara ti won. Helen n tesiwaju ninu onje ti o n se. o si wo oko re fun igba die, lehin naa o bere si so oro si.**

**Helen:** iwo ko tile so n kankan nipa ibi ise re loni

**Peter:**( **o wo oke**) ko si ohun kan lati wi, ise si gba omi mu sibe.( **o bere si ka iwe iroyin re lo**)..

**Helen:** emi na ti se akiyesi, e ko tile ri aye duro si ile rara, a ko tile ri aye lati ri ara wa dada.

**Peter: ( o si n ka iwe re lo)** jowo ki li o wi.

**Helen : ( o gbe ohun soke die)** mo wipe a ko ri aye lati fi ikuluku.

**Peter :( o pa iwe re de, o si dide)** olufe owon, emi naa mo. Ise yi li o gba omi mu die. Sugbon li kete ti a ba ti pari ise ti a n se lowo bayi, iwo naa a gbadun mi doba **(Peter fi owo re ko aya re)**

**Helen: (o gbe ori le aya oko re)** sugbon igba wo gan li ise naa yio dopin. Se ni won maa n fun o li ise kan lehin ti o ba ti n pari ikan. Emi nikan ko ni o nilo akoko re, mo fe ki o wa aaye fun Alex naa, omo re. Gbogbo igba ti o be ti de lati ile iwe li o maa n bere ibi ti o wa, emi ko si li mo esi tie mi yio fun. **(o gbe oju soke , o si wo oko re).** Ki o to wole li ale, yio ti lo sun. emi ko mo ona ti n ba fi se alaye fun o . Ki ni yio tun sele ni igba ti mo ba tun bi oyun inu mi yi tan, ti awon mejeji ba tun n bere baba won.

**Peter : ( o fa si eyin die, ohun re si le si).** O dara, emi ko mo ohun ti n ba wi. O soro ki n wa li enu ise, ki n tun wa li ile ni igba kan naa. Mo mo daju wipe Alex yio mo li ojo kan wipe ki aye re le dara li mo fi n se ise kara bayi, emi kan yi naa li ma san owo ile iwe re, abi bee ko. **( oju Helen naa bere si le si, Peter si re ohun re sile die si).** O dara, ma fi se ibinu. Iwo naa mo wipe nkan ko rogbo fun mi bayi. N je o mo nka, emi yio wa aye fun yin li opin ose yi, a le sere jade , koda a le lo si ile ti a n ko awon eranko pamo si. Alex yio feran lati lo dajudaju.

**Helen: ( o rerin muye)** o ti dara niyen, inu Alex naa yio dun gidi.
**( ero ibanisoro kan bere si ni pa ariwo)**

**Peter** : Jowo aya mi, je ki n dahun si ipe yi ( **o fa ero ibanisoro kan jade lati inu apo aso** re). E n le o, mo ti gbo. Emi naa ko nip e lati de ibe, beeni. Emi ko le si ona ibe, o ti dara. Emi naa a ri o li aipe.

**Helen :** Se ise ti tun ya ni?

**Peter : ( o gbe ewu re wo, o si bere gbe apo re)** Bee ni, jowo fo iye denu. Mo ni lati pada lo si ibi ise. Ko si elomiran to si le se ise naa. A ni lati se kia kia. O se se ki a ri igbega lehin ise yi, eyi yio sit un mu owo wole fun wa si **( o fi enu ko aya re li enu)**

**Helen :** o se se ki n ti lo sun ki o to de o.

**Peter :** emi naa yio ta o ji ni igba naa. **( O jade lo).**

**Helen : ( o boju wo oyun onu re)** ko ti le bere nipa iwo loni. **( o bere si ni se onje re lo).**

**IFIHAN KEJI.**

**A ri ile itura kan, ero po nibe gidi. A n gbo orin kikankikan. Awon eniyan si n mu oti, ti awon miran si n jo. A ri obinrin arewa kan nibe, o n mu oti, a si kiyesi wipe o n duro de enikan ni. O si apo ipamowo re, o mu digi ati itote jade, o sib ere sit un ujo re se. o sa n wo enu ona bi wipe o n reti eniyan kan.**

**Osise ile oti :** Se e ti dide ni.

**Tina :** rara o , kama ri.

**( bi o ti wo yika li ekan si, Peter wo inu ile itura naa, o ngbe apo re dani. Peter wo yika titi o fi ri arabinrin Tina. O si rin lo si odo re)**

**Tina: (o wi fun osisi ile itura naa)** Se bi mo wi fun o. **( o yi pada o si so fun Peter)** E pele o, ki lo de ti o fi pe o to bayi **( awon mejeji fi enu konu)** iwo kip e to bayi.

**Peter:** ohun kan lo dami duro, sugbon mo sa ti de ti de bayi.

**Tina :** a bi aya re lo da o duro ni. Mo mo wipe se li o tun gbe odu fun bi o ti maa n se tele. Arabinrin yen ko mo nkankan! Emi ko je gba iru re lai.

**Peter :** o ti dara o, mo dupe ti emi naa ko fi o se aya, aya mi ko mo nkankan. Se ni o ro wipe ise lo gba omu mi gidi. ( **Peter bere si ni fi ofo pa ara Tina)** Koda bi a ba tile ka emi ati iwo mo, o to be , o ju be lo**. (o fa Tina mo ara re, o si fi enu ko li enu ).** Se ile re ni ipade loni ni?

**Tina ( o rin erin muye)** se ko tile si ohun miran ti o n fi inu re ro ni?

**Peter :** emi ki fi akoko sofo o, emi a maa tara kiakia ni. Se bi ihun ti won ti mo mi si li ibi ise wa ni.

**Peter fi owo re ko Tina, awon mejeji si jade kuro li ile itura naa.**

**IFIHAN KETA.**

**A ri Peter ati Tina ninu iyara kan, awon mejeji n ba ara won se ere ife. Aso to fere bo kuro li ara awon mejeji patapata. Kado se ni tina ti ju apo ipamowo re si egbe kan.**

**Tina**. **( o sun seyin kuro li odo Peter, o gbe apo ipamowo re, o so yo oro idaabobo kan jade)** N je a le wo inu ibusun lo, yio tu ni lara ju ori aga yi lo o.

**Peter :** ko buru. **( o se akiyesi ora idaabobo li owo Tina).** Ki ni eyi wa fun?

**Tina :** mo li ero wipe a ni lati bere si ni so ara wa bayi o. emi ko fe ni oyun, n ko si fe wahala kankan.

**Peter :** Sebi o ti n lo oogun ifetosomobibi ?

**Tina :** Beeni, sugbon awon ewu miran wa pelu, eyi ti oju nini oyun lo, bi awon aarun ti ale ko lati ibi ibalopo. Emi ro wipe a ni lati so ara wa o.
**Peter** : Ki ni ani lati ma daamu ara wa li tori awon aarun kan. Sebi iwo ati Helen li mo n ba ni ibalopo. Mo si mo wipe ko si okan ninu yin ti o ni aarun lara. Se o n so fun mi wipe o ti n baa won okunrin miran jade ni ?

**Tina : ( oju re daru die)** Rara o , sugbon mo sa ti ni awon okunrin miran tele, beni iwo naa ti ni awon obinrin miran seyin. Oro yi ko yo enikeni sile ninu wa o. Emi ko si ti se ayewo ara mi tele, abi iwo ti se ayewo ara re ni?

**Peter :** Rara, sugbon mo mo wipe emi ko nilo ayewo kankan, beni ni iwo naa ko nilo ayewo kankan. **( o fi enu ko li enu, o si yo roba naa kuro li owo re)** wo ati n se kini yi ti to igab die bayi. ti o ba ti ko aarun kankan ni, o ye ki a ti ri apere re bayi, a bi bee ko ni? Emi si n gbadun ibalopo lai lo roba rara, abi se iwo ko mo wipe lilo roba yi le din igbadun ku ni ?

**Tina :** emi naa ro bee. Sebi a sa ti n se lai lo nkankan lati ojo yi. Ti o ba si je wioe mo ti ko aarun ni, o saa ye ki o ti maa re mi diedie. Emi pelu si n gbadun re lai lo roba kankan. **( awon mejeji tesiwaju lati ma ba ara won lo po).**

**Peter : ( o fa Tina dide, o si ju roba naa si ori ijoko)** Bee ni, igbadun yen ko legbe. O ya je ki a wo inu ile lo. **( awon mejeji si wo inu yara lo**).

## IFIHAN KERIN.

**Lehin osu die. A ri Tina ninu ile, o da joko sibe. Ero ibanisoro re bere si n pa ariwo.**

**Tina :** E pele o. **( o se oju bi wipe ko mo eni to n soro ninu ero re)** Graham? Se iwo ni? Se alaafia ni o? **( o mi ori, inu re dun )** o ma to ojo meta, o ye ka ri ara wa o. Igba wo li wa ri aaye? **( o dake die)** se osan oni ti dara? **( o dake die)** Graham, se ko si nkan, mo se akiyesi wipe ohun re lo sile die **(o dake die)** ko buru, iwo yio so fun mi ohun ti o sele ni igba ti a ba ri ara wa. **( o dake die**) O di igba ti a pa pade o.

## IFIHAN KARUN.

**A ri Graham ni ile itura kan. O bere si ni wo kaakiri. Ko  pe ti Tina si wole wa. Graham dide lati ki ku abo.**

**Tina :** e ku ojo meta o ( **won di mo ara won**) inu mi dun lati tun ri o, ojo tip e o?

**Graham :** o ti to nkan bi osu meta bayi ( **awon mejeji joko**).

**Tina : ( o pe osise ile itura kan).** N je a le ri ohun mimu bi**? ( o ko oju si Graham)** ibo li o ti wa lati ojo yi . igba odun keresi ni mo ti ri o gbeyin, se bi o ti de lati irin ajo ti o lo ni igba yen?
**Graham ( ara re ko bale)** beni  ( **o dake die**) sugbon mo tit un lo si  Idonesia , Thailand, India. Mo ti baa won eniyan oade lopoplopo, mo si ti ni awon ore gidi.

**( osise ile itura naa pade de pelu ohun mimu fun Tina)**

**Tina :**  N je o ba eni keni pade ti o se Pataki si o bi?

**Graham : ( ara re ko bale rara)**  o ti o o, ki ni idi ti o fib ere?

**Tina :** mo kan n bere ni. Mo mo wipe ko si eni kankan ti o ba pade, bi bee ko, a ko ni gbadun ara wa li akoko odun keresi to koja

**Graham :** wo arabinrin, oro wa o, oro naa si po. Mo ni iroyin buburu kan fun o .

**Tina :** ki lo sele?

**Graham** : li akoko to mo lo si irin ajo yen , mo ni ibalopo pelu awon eniyan kan. Opo won naa je arinrin ajo. Emi ko ro jinle dada ewu to wa ninu ohun ti mo n se.

**Tina :** ki li koko oro re?

**Graham** : ni igba ti mo de ile, mo ro wipe o ye ki n lo se ayewo ara mi, lahin ayewo naa, a so fun  mi wipe mo ti ko arun Chlamydia o

**Tina ( oju re daru)** Graham, ki lo n so eyi fun mi si?

**Graham: (o n wo ile)** emi ti le ko arun yi ran iwo naa nigba ti a ni ibalopo li ojo aisuun keresi, sebi a ko lo roba kankan. O sese ki arun yi ti ran iwo pelu, ati gbogbo awon ti o ba ti ba o lo po lehin  **( o dake die)** se iwo ko ni elomiran ni?

**Tina :** mo ti ri awon eniyan miran lehin re, mo n ri awon meji bayi, sugbon ko si idamu kankan.

**Graham :** mo nilati so fun o, o ye ki iwo naa mo si oro yi. O se Pataki I iwo naa lo se ayewo ara re. ko soro lati se itoju arun Chlamydia, enu oogun li iwo naa a ni lati lo. O sit

un se Pataki wipe , ti a ba ri arun yi lara re, o ni lati so fun gbogbo awon ti o ti ba o lo po lati lo se ayewo ara won pelu.

**Tina :** ki n lo so fun won!?

**Graham** : beni o, o se pataki. Idi ni wipe ti a ko ba tete se itoju arun naa, o le fa awon wahala bi airomobi o. bi iwo ko ba mo bi iwo yio se wi fun won, awon onise ile iwosan ti o ba lo le fi ogbon so fun awon eniyan bee, ti won ko si ni daruko re rara ( **o dide).** Gbo mi, o se ni laani wipe emi ni mo n fun o ni iroyin buburu yi o, sugbon mo ti fe maa lo.

**Graham bere si lo, o fi Tina sile ni ile itura naa.**

## <u>IFIHAN KEFA.</u>

**A ri ile iwosan kan. A ri Tina , o joko , eru si wa li oju re. O mu iwe kan dani, sugbon ko le ka iwe naa.**

**Noosi kan wo inu ile .**

**Noosi :** Tina Barret da!

**Tina dide , o si wo ile to noosi naa lo.**

**Julie** : e ple o, oruko mi ni Julie, mo je okan ninu awon noosi to n sise ni ile iwosan yi. Mo fe bi o li awon ibere kan nipa ara re, emi yio si fe ki o fun mi li idahun li tooto ki a ba le mo iru awon ayewo ti iwo yio se. N je o fi ara mo eyi?

**Tina :** ko buru.

**Julie ;** Tina, n je o ni eni kan ti on ba ni ibalopo, abi iwo a maa ni ibalopo pelun awon eniyan miran bi?

**Tina:** Umm … o da bee. Mo ni eni kan, ohun nikan ko, mo tun ni elomiran pelu, sugbon a kii ri ara wa pupo. ( **o dake die)** ohun to sele ni wipe, mo ni ibalopo pelu enikan laipe, eni naa ki se okan ninu awon ore mi, sugbon o pada wa so fun mi wipe ohun n gba iwosan fun arun Chlamydia.

**Julie :** iru ibalopo wo ni o ni pelu won?

**Tina :** orisirisi naa li a se o

**Julie :** n je o lo roba idaabobo, se iwo a maa lo roba li akoko ibalopo?

**Tina :** rara o, emi ko lo roba. Emi n lo oogun ifetosomobibi, emi ko si ro nkankan nipa lilo roba o.

**Julie :** Tina, o se Pataki lati lo roba idaabobo ni igbakugba ti o ba n ni ibalopo. Ki se tori ki a ma ni oyun nikan ni a se n lo roba o, sugbon nitori awon arun ti a le ko lati ibi ibalopo pelu. Ni afikun, ki se gbogbo igab ni a ma n ri apeere wipe a ti ko arun o. ( **o dake die ).** Ti a ko ba si tete se amojuto awon arun wonyi, o le se okunfa awon arun miran bi arun HIV. Ohun ti a se nisiyi ni wipe, emi yio se awon ayewo kan fun o. emi yio se ayewo eje pelu ayewo ito re. Ayewo ito yi wa fun arun Chlamydia ati arun atosi, ti ayewo eje wa fun arun HIV anh syphilis. N je iwo fe se awon ayewo yi?

**Tina :** ko buru, se bi ti mo ti ko arun HIV emi yio sa ti mo, abi?
**Julie :** ko ro be o, kokoro HIV le gbe ara eniyan fun igba pipe ki a to ri apere re o. Ayewo eje yen se Pataki gidi, eyi ti a ko le ku gbuuru se o nitoripe oje ayewo fun HIV. Iwo si mo wipe arun yi ko ti no oogun lati wo o. Sise ayewo fun HIV si ni awon anfaani, ati awon aleebu o.

**Tina :** Bi kini o?

**Julie :** awon anfaani to nibe po. N je ti ayewo naa ba fi han wipe eniyan ti ni arun HIV, eniyan yio ni anfaani lati gba awon itoju eyi ti o le mu emi eniyan gun si. Awon orisi oogun tuntun si lo n jade li ojoojumo eyi ti eniyan si le je anfaani won. O ye ki eniyan ri wipe ohun gbe igbe ayewo to ni itum pelu arun yi, eniyan nilo ifowosowopo lati odo awon ara pelu. Eniyan yio ni aye lati se awon ipinnu kan, lara won ni ipinnu lati bi omo, nitoripe awon omo ti a ba bi bayi le fi ara ko kokoro yi lara iya won. Eniyan yio ni aye lati so fun awon ti o ba ti ba ni ibalopo ri wipe o ti ko arun yi, a si le ran eniyan lowo lati se eyi pelu ogbon, bakanna , eniyan le se ipinnu lati ma ni ibalopo mo rara, tabi ki a ri wipe a n lo roba ni igba gbogbo ti a ba ni ibalopo. N je ti ayewo ba fi han wipe eniyan ko ti ko arun yi, yio fun o niaye lati bere si ni ko ara eni ni ijanu gidi ki a ma baa ko arun yi. Ranti wipe , ko si ohun kan ti ale ri toka si wipe iwo naa ti ko arun yi.

**Tina :** mo ti gbo o, sugbon awon aleebu wo lo wa ninu sise ayewo yi o.

**Julie :** n je ti ayewo yi ba fi han wipe o ti ko arun yi, o le ba eniyan lokan je gidi. Sugbon gbogbo re da lori iru ifowosowopo ti eniyan ba ni pelu awon ara ati ore. N je o ni awon eniyan ti o se fi ara ti li ayika re rara ?

**Tina :** emi ati iya mi gbo ara wa ye gidi. Emi ko ti so fun bi mo se n lo igba mi o. emi nikan lo mo bi mo se n lo igba mi. Sugbon emi ko fe doju ti iya mi rara o. koda iya mi ti n ro wipe o ye ki emi naa ti ni oko emi naa o.

**Julie :** emi ro wipe, ti ayewo ba fi han wipe o ti ko arun yi, iwo yio ni lati gbe ara le iya re fun ifowosowopo . Ti ayewo yi ba fi han wipe o ti ko arun yi, o le ba eniyan lokan je gidi. Orisirisi idamu okan li o le sele si eniyan. Irewesi le ba eniyan, ibanuje, ati bebe lo. O se Pataki lati mo wipe ti eniyan ba ti ko arun yi, iru eni be ni lati se opo atunse ona ti eniyan fi n gbe aye re. Awon ara ile eniyan pelu yioi si fi ara gba lara awon isoro wonyi, yala won ti ni arun yi tabi won ko ni.

**Tina :** o ma ga o, ipinnu nla ma ni eyi je. **( o dake die),** emi ko tile mo ohun ti n ba se.

**Julie :** ma se iyonu rara, ko si ikanju lati se ayewo yi. Iwo sa ti ro awon nkan ti a ti so jinle, ki o si se ohun ti okan re bay o si. Ranti wipe awa ki yio tu asiri ti o ba wu ki o so fun wa sita**. ( o dide**). Jowo je ki n lo wa ohun mimu die, iwo sa ti ronu si oro yi, ki o si je ki n mo ipinnu re nigba toi mo ba pada de.

**( Julie jade kuro ninu yara, o fi Tina nikan sile sibe).**

**Tina : ( o n ba ara re soro)** se ti ayewo ba wa so wipe mo ti ni kokoro HIV, emi yio wa ni lati lo so fun gbogbo awon ti a ti job a ara wa lopo, bi Peter, Graham, Tony. Emi le ma so fun won o, sebi noosi yen le so fun won. Sugbon kini awon eniyan yio ma ro nipa mi o?. Emi yio wa ma nikan doju ko isoro ji titi, iru oju wo ni awon eniyan yio ma fi wo mi. emi yio tun ni lati maa lo oogun ni ojojumo, won si so wipe awon oogun yen le die. N je emi yio tile le se ise kankan mo? Bawo ni mo se fe bi omo temi, li ona ti won ko se ni ko arun yi lati ara emi iya,. Bawo ni emi yio se wi fun iya mi o, inu re yio baje gidi o. o dabi wipe yio kuku dara ki n ma mo ipo ti area mi wa o, ohun ti n o se gan niyen o **(o dake die ).** Sugbon ti o ba tile je wipe mo ti ko arun yi, seni emi yio ma ko ran awon eniyan kaakiri, n je ti mo ba tile pade eni ti mo feran gidi, ti mo so lo ko arun yi ran laimo, nitoripe emi ko lati se ayewo ara mi. awon ti mo ni nisiyi nko. Peter ni aya ati omo, n je emi ko ni koarun yi ran, o si sese ki o ma I ti ni arun yi o. Olorun maje, emi ko ni arun kankan**, ( o dake die** ), sugbon o ma ye ki n se ayewo yi **( o dake die ),** emi yio se ayewo yi o

**( Julie wo inu ile pada, o si gbe ohun mimu dani)**

**Julie :** n je o ti pinnu lati se ayewo yi rara. Ranti wipe ko si idi fun o lati kanju o, aye wa fun o lati pada wa li ojo miran fun ayewo yi, ki o le ri aye lati ro inu re gidigidi. A o kan se ayewo fun Chlamydia ati arun atosi ti eyi ba wu o.

**Tina: ( eru wa li oju re)** ko buru o, mo ti ro oro naa, mo sir o wipe gbogbo ayewo wonyi li o ye ki n se. o se se ki n ma ti ko arun yi, sugbon ti n ba ti ko, o sa ye ki n mo, abi.

**Julie :** se o da o loju o**? ( Tina mi ori )** ko buru, emi yio se ayewo eje naa bayi, emi yio si gba ito re pelu. Emi yio si fe ri o li ose kan oni lati fi esi awon ayewo naa han o, ati lati dahun awon ibeere to wu ki o ni.

**Tina :** e se o.

**<u>IFIHAN KEJE.</u> Lehin ose kan.**

**A ri Tina ninu ile iwosan, o n joko de awon osise.**

**Noosi :** Tina Barrett !

**Tina dide, o si wo inu iyara itoju lo, arabinrin kan na si wole to pelu noosi .**

**Julie :** Tina, arabinrin Jayne niyi, okan ninu awon agbani ni imoran wa ni, N je o fe ki o wa pelu wa nibi?

**( Tina mi ori. Gbogbo won si joko)**

**Julie :** Tina, ohun ti a wa se li lati soro nipa awon esi ayewo eyi ti ose **( o dake die).** Ayewo naa fi han wipe o ni arun ti an pe ni Chlamydia. Awon oogun wa lati se itoju iru arun yi.

**Tina :** iru arun ti Graham so wipe ohun na ni ni eyi, se o toi ni wipe arun ti o ni oogun ni?

**Julie :** bee ni **( o dake die ).** Sugbon Tina, a se ni laanu wipe ayewo naa tun fi han wipe o ti ko arun HIV o. **( oju Tina daru ).**

**Jayne :** Tina , mo mo wipe ajalu ni eyi yio je fun o, sugbon mo fe ki omo wipe awa mejeji yio ba o fi owo so owo po bi o ti ye. A o se ipese awon oogun fun o lati lo. Ranti wipe op awon eniyan li o ni aarun yi, ti won si n gbe igbe aye to ni itumo sibe.

**Tina dake jee.**

**Jayne :** emi yio bere si ri o loorekoore lati igba yi lo, o si ni aaye lati so ohun to wu ki o fe fun mi. o lie to lati ri mi ni igba yow u, eyi ni fun o lati le bami fi ikuluku.

**Julie :** emi naa si setan lati dahun gbogbo awon ibeere yowu ki o ni, ko ni se iwo nikan o. Tian n je o fe ki a pe eni keni bi. Tina mi ori, o je ajalu fun, o bere si nig bon diedie. Lekan na, o bere si sun ekun.

**Jayne si ro mo.**

## <u>IFIHAN KEJO.</u>

**A ri Peter ninu ile ise re. Ero ibanisoro re bere si ni pa ariwo.**

**Peter :** e pele o

**Julie :** e pele o, n je mo le ba Peter Thompson so oro bi ?

**Peter :** mo n gbo o.

**Julie :** e pele o Peter. Emi Julie lo n soro, mo je okan ninu awon noosi li ile iwosan Wakefield. N je mo le ba o soro bi?

**Peter :** umm…. Beeni, ejowo se ko si nkan o?

**Julie :** Peter okan ninu awon obinrin re wa si ile ise wa lati se awon ayewo fun arun ti a le ko lati ibi ibanilopo, ayewo si fi han wipe o nia won arun kan lara. Idi ti mo fi n pe o ni lati so fun o lati lo se ayewo ara re pelu. N je ti o ba ni iru awon arun wonyi, ki o le ri itoju to peye gba. Ko di dandan ki o wa si odo wa nibi, o le lo si odo awon dokita ti o ba wu o li agbegbe wa yi.

**Peter :** e duro o, se o n fi yemi wipe emi naa ti ko arun ni, ta li o wa ri o, ni igba wo ban ni?

**Julie :** arakunrin, awa ko le so fun o eni yo wu to wa ri wa, tabi akoko ti iru eni bee wa ri wa. Ohun ti a n so ni wipe, ni iwon igba ti o ba ti ni ibalopo lai lo idaabobo, o se Pataki ki o se ayewo to kun oju osuwon o.. o se se ki a mamri ohun kan ni ara re, sugbon a se Pataki ki a ye o wo o.

**Peter :** emi ko le gba eyi gbo o. N je mo le ri yin lati ye ara mi wo bi ?. N je e le so fun mi iru arun ti mo ni?

**Julie :** bee ni, o le wa ri wa o.O se se ki o ti ko arun Chlamydia, eyi to je arun ti o gbo oogun. Ni igba ti o ba ri wa, awa yio se ayewo ti o peye fun o, a o si fun o li iru oogun to ba ye.. N je o fara mo eyi ? N je o fe lati wa ri wa li ose yi? Aye wa li ojo alamisi ni nkan aago marun aro.

**Peter :** o ti dara, emi yio gbiyanju lati wa li ose yi, li akoko ti e so yen gan. E se pupo, o digba o. ( **Peter gbe ero ibanisoro re sile, o si bere si nib a ara re soro ).** Ka ma ri o ! iru ewo ni eyi o, akoko tie mi yio ni ale niyi, mo si ti yak o arun ( **o bu serin** ) awon miran a tile niale bi marun ti won ko si ni ko arun kankan lati ara won. ( **o dake die**). A bi ijiya li eyi je fun mi, emi ko tile mo eni yow u ti mo ba ni ibalopo o ( **Peter bere si ni ro inu** ) O a le je Tina bi, ko sa ni elomiran afi emi nikan ( **o dake die**) o ni lati je Gemma, o n li o jo aja igboro ju, beni ko so fun mi iye awon eniyan ti o ti ba jade. Oku oorun.

**<u>IFIHAN KESAN .</u>**

**A ri Peter ni ile iwosan , o wa pelu Julie ati Jayne**.

**Peter :** e jowo o, oro yin ko fe ye mi dada o

**Julie :** Peter, ayewo eje ti a se fun o fi han wipe o ti ko kokoro HIV.

**Peter : ( ara re ko bale mo)** Kokoro to n fa arun AIDS ? kokoro to n fa arun AIDS.

**Jayne :** sugbin awa le fun o ni iranwo lati la eyi koja , opo ni awon anfaani to si sile fun o, ko ni se iwo nikan o.

**Peter ko tile gbo ohun ti won n so mo, se li  o ka owo mo ori.**

**Peter :** ( **o ka owo mo ori sibe, o bere si ni pa eyin keke).** Ta li o fi iru eyi semi?, ta li o ko iru eyi ran mi ? e gba mi o.

**Julie :** o soro lati dahun ibere yi o, papa ti o ba ni ibalopo pelu opo eniyan seyin, eyi ti opo eniyan ti se . Ati wipe se ni ki o wo iwaju, ki o wo ona abayo ninu ipo ti o wa yi o.

**Peter : ( o gbe oju soke )** bawo ni emi ko se ni ronu ? , mo ni aya sile, mo ni omo sile. Iyawo mi tile wa nino oyun bayi. Bawo ni emi ko se ni ronu eni ti  o ko iru ajalu yi ba mi.

**Jayne :** mo mo wipe o soro gidi, sugbon awin idile re gan le fun o li iranwo to ye o, won le ran lowo gidi. Mo mo wipe o soro lati ro o, sugbon o se Pataki ki o mu ayta re gan wa fun ayewo o, o si ye ki o so fun aya re esi ayewo ti a se fun o.

I**damu  ba Peter ju ti ateyin wa ni igba to gbo eyi, ko tii ro nipa eyi tele.**

**Peter** : se ya mi naa yio ti ko arun yi ni,  a mo gbe o.

**Julie :** ko di dandan wipe aya re ti ko kokoro yi o, sugbon nitoripe eyin mejeji ti no ibalopo, o ye ki a se ayewo fun ohun pelu, papa tori wipe o wa ninu oyun bayi o.

**Peter . ( o n wo ile, o ka owo mo ori side) ahh olorun o !**

## <u>IFIHAN KEWA .</u>

**A tun ri ile Peter ati aya re  Helen. Helen joko sibe , o si n ka iwe kan. Omo won Alex n sare kiri inu ile , o n sere. Peter wo inu ile, oju re ko si fani mora rara.**

**Helen : ( o gbe oju soke )** e ku abo o, ise n ko o **? ( o ri bi oju oko re se ri** ) Peter se  ko si nkan o, bawo ni oju re se ri bayi?

**Helen fe dide, sugbon oko re ko je, Peter joko si iwaju re, o si gbe apo re sile.**

**Helen : ( oju re ti daru pelu )** se kosi n kan o, kilo sele, abi won ti gba ise lowo re ni ?

**Peter :** oro ise ko o ( **oro bere si ni ko ni enu )** mo ni ohun kan lati fi to o leti o, mo si fe ki o fi eti re sile si mi o, mo ko abamo gidi o, mo ti ko abamo o.

**Orin kan bere si jade lati eyin. O ko  gbo ohun ti awon osere n so mo. Peter n sun eku  gidi bi o ti n soro. Idamu ba Helen gidi, o bu si ekun kikoro. Omo won Alex naa**

**si mo wipe ohun kan n sele ninu ile won, se li o dake ere to n se, o si gbe owo re le iya re. Helen boju woo mo re , o si gbe le itan re. Helen ati Peter bere si wo ara won, won ko mo ohun ti won ki ba so si ara won**

**IPARI.**.

Translated into Yoruba Language by:
Dr. Adeoti, Abolaji.
Pretoria, South Africa.
5th/FEB/2008.